# JESU, OLURAPADA WA

## Heberu 1: 1 – 14.

### ĘKỌ 432 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nitorina ẹ lọ, ẹ ma kọ́ orilẹ-ède gbogbo, ki ẹ ma baptisi wọn li orukọ Baba, ati ni ti Ọmọ, ati ni ti Ẹmi Mimọ́" (Matteu 28:19).**

**A Mu Awọn Irubọ Ṣẹ**

A kọ Iwe Heberu lati ọwọ Paulu Apọsteli si awọn Heberu ti i ṣe Onigbagbọ́, awọn ti o ti gba Jesu gbọ́. A ti kọ́ wọn lati pa Ofin Mose mọ́, wọn si mọ̀ nipa gbogbo irubọ ti wọn gbọdọ ṣe. Ṣugbọn irubọ wọnyii ni a ti fi fun wọn gẹgẹ bi aworan, lati fi han awọn eniyan ti o wà ni akoko Majẹmu Laelae pe Jesu yoo wá lọjọ kan lati ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ lati ra araye pada kuro ninu ẹ̀ṣẹ. Nigba ti Jesu dé, O ṣe gẹgẹ bi apẹẹrẹ ti ẹbọ wọnni ti fi hàn: a kan An mọ́ agbelebu ni Kalfari, O si ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ. Lẹyin eyi, kò tun si idi ti o le fa fifi ẹran rubọ mọ́.

Ninu awọn ori ti o bẹrẹ iwe Heberu Paulu ṣe alaye nipa ogo Ọlọrun ati ti Jesu. Ọpọlọpọ awọn Ju ti o wà ni ayé nigba ti Jesu wà ni ayé ni kò gbagbọ pe Ọmọ Ọlọrun ni Oun i ṣe. Paulu paapaa kò gbagbọ́ nigba ti o kọkọ gbọ́ nipa Jesu; ṣugbọn nigba ti o ye e ti o si ni iyipada ọkàn, gbogbo ayé rẹ̀ ni o lò lati fi hàn fun awọn ẹlomiran pe Ọmọ Ọlọrun ni Jesu i ṣe.

**Awọn Wolii Majẹmu Laelae**

Ni ibẹrẹ itan araye, Ọlọrun a maa ti ipasẹ awọn wolii sọrọ. Mose jẹ wolii; bẹẹ ni awọn miiran tun wà pẹlu: Samuẹli, Jeremiah, Isaiah ati Esekiẹli. Awọn wolii miiran sọrọ, sibẹ gbogbo wọn fi ohun ṣọkan ninu ohun ti wọn sọ nitori Ẹmi Mimọ́ ni o sọ ohun ti wọn n wi fun wọn. Peteru Apọsteli sọ nigba kan pe: "Asọtẹlẹ kan kò ti ipa ifẹ enia wá ri; ṣugbọn awọn enia mimọ Ọlọrun nsọrọ lati ọdọ Ọlọrun bi a ti ndari wọn lati ọwọ Ẹmi Mimọ́ wa" (2 Peteru 1:21). Awọn wolii ti Paulu sọrọ nipa rẹ̀ ni ọrọ yii n tọka si.

Gbogbo awọn wolii ni o ti sọrọ nipa wiwá Jesu. Nigba miiran wọn sọ nipa akoko ti yoo wá gẹgẹ bi Ọmọ-ọwọ́ ni Bẹtlẹhẹmu; nigba miiran wọn a sọ nipa akoko ti yoo pada wá lati kó awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀ lọ; ti yoo si tun pada wá lati wá jọba ni ayé ni igba ijọba Ẹgbẹrun Ọdun.

**Ajogun Ohun Gbogbo**

Lakotan Jesu dé, O si sọ fun wa ohun ti Baba n fẹ ki a mọ̀. Jesu tobi ju gbogbo awọn wolii lọ -- ni tootọ, O tobi to bẹẹ ti O fi ṣe iranlọwọ paapaa lati dá ayé ati ohun gbogbo ti o wà ninu ayé. Ọlọrun Baba ti yan Jesu lati jẹ ajogun "ohun gbogbo", itumọ eyi ti i ṣe pe igba kan n bọ̀ ti Jesu n bọ̀ wa ṣe akoso ayé, olukuluku eniyan si ni lati ṣe ohunkohun ti O ba paṣẹ fun wọn lati ṣe. Ohun gbogbo yoo jẹ ti Rẹ, yoo fi anfaani fun awọn ọmọ Rẹ (gbogbo awọn oloootọ ọmọlẹyin Jesu) lati ba A ṣe akoso ayé. Dafidi sọ nipa akoko yii nigba ti o kọ akọsilẹ fun Ọlọrun: "Bère lọwọ mi, emi o si fi awọn orilẹ-ède fun ọ ni ini rẹ, ati iha opin ilẹ li ọrọ̀-ilẹ rẹ. Ọpá irin ni iwọ o fi fọ́ wọn; iwọ o si rún wọn wom-wom, bi ohun èlo amọ̀" (Orin Dafidi 2:8, 9). Ọlọrun yoo fi gbogbo agbára wọnni fun Jesu.

Paulu sọ nihin yii pe Jesu ni ipá lori ẹda ayé: "nipasẹ ẹniti o dá awọn aiye pẹlu." Johannu Apọsteli sọrọ bakan naa nigba ti o wi pe Jesu ni Ọrọ naa, O si di ara O si n ba wa gbé. "Li àtetekọṣe li Ọ̀rọ wà, Ọ̀rọ si wà pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si li Ọ̀rọ na. On na li o wà li àtetekọṣe pẹlu Ọlọrun. Nipasẹ̀ rẹ̀ li a ti da ohun gbogbo; lẹhin rẹ̀ a ko si da ohun kan ninu ohun ti a da" (Johannu 1:1-3). Jesu wà lọdọ Ọlọrun nigba gbogbo.

Ninu Ọrọ Ọlọrun ti Paulu tọka si: "Iwọ li Ọmọ mi, loni ni mo bi ọ" (Orin Dafidi 2:7), Ọlọrun n tọka si akoko ti a bi Jesu ni Bẹtlẹhẹmu, nigba ti O wá si ayé ni awọ̀ eniyan. Jesu tikara Rẹ jẹ ki awọn ọmọ-ẹyin Rẹ mọ pe Oun ti wà ṣaaju wiwá Oun si ayé. Ninu adura Rẹ gẹrẹ ṣaaju ki a to kan An mọ́ agbelebu, O beere lọwọ Ọlọrun: "Baba, ṣe mi logo pẹlu ara rẹ, ogo ti mo ti ni pẹlu rẹ ki aiye ki o to wà" (Johannu 17:5).

**Ogo Jesu**

A ko le mọ bi ogo ati agbara Ọlọrun ti tobi to ṣugbọn bi o ti le ga to ni, bakan naa gan an ni ogo ati agbara Jesu to. Ki i ṣe pe Oun pẹlu Ọlọrun ṣiṣẹ nipa didá ayé nikan, ṣugbọn nipa agbara Rẹ̀ ni o n mu ki ayé ati awọn irawọ ati awọn ẹda ọrun maa yipo ni àye wọn. Ṣugbọn eyi ti o kàn wa ju lọ ni pe, ohun ti o tobi ju lọ ti Jesu ṣe ni iku ti O kú fun ẹ̀ṣẹ wa, ki awa ma ba a jiya ninu ọrun apaadi fun awọn ohun buburu

ti a ṣe.  Nitori Jesu kú fun ẹ̀ṣẹ̀ wa, a le bẹbẹ pe ki O dari ẹ̀ṣẹ̀ wa ji wa;  Oun a si dari ji,  a si wẹ ẹ̀ṣẹ̀ wa nù, a si sọ wa di olododo niwaju Ọlọrun bi ẹni pe a ko i ti dá ẹ̀ṣẹ̀ kan ri.  Lẹyin ti O ti pari iṣẹ nla yii, O pada si Ọrun, O si joko ni ọwọ ọtun Ọlọrun.

### Ẹni Mẹta ninu Iwa Ọlọrun

Awọn miiran a maa waasu pe Ẹni kan ṣoṣo ni o wà ninu Iwa Ọlọrun: Jesu nikan ṣoṣo. A ti ṣe akiyesi pe Ọlọrun sọrọ nigba ni nipasẹ awọn wolii, ṣugbọn ni igba Majẹmu Titun O ti ipasẹ Jesu sọrọ. Pẹlupẹlu, Jesu gbadura si Baba (ki i ṣe Oun tikara Rẹ̀ ni O gbadura si)  O si beere pe ki O fi ogo ti Oun ti ni tẹlẹ **pẹlu** Baba ni Ọrun hàn fun awọn ọmọ-ẹyin Oun.  Bi Baba bá wà, ti Ọmọ si wà, eyi fi Ẹni meji hàn.  Lẹyin ti Jesu pari iṣẹ Rẹ ni ayé O joko ni ọwọ ọtun Ọlọrun -- lọdọ Ẹni miiran.

Ẹni kẹta tun wà ninu Iwa Ọlọrun kan naa, Ẹmi Mimọ́.  Awọn Onigbagbọ́ a maa lo ède Mẹtalọkan lati tọka si Ọlọrun Baba, Ọlọrun Ọmọ, ati Ọlọrun Ẹmi Mimọ́. Olorin kan wi bayii pe:  “Ologo mẹta, lae Olubukun!” Ẹmi Mimọ́ paapaa ni ipa ninu didá ayé, nitori Iwe Mimọ́ wi pe: “Ẹmi Ọlọrun si nràbaba loju omi”  (Gẹnẹsisi 1:2).  Nigba ti  a dá eniyan,  Ọlọrun wi pe, “Jẹ ki a dá enia li aworan wa, gẹgẹ bi irí wa” (Gẹnẹsisi 1:26).  Nigba ti a ba n lo awọn ọrọ wọnyii “a”ati “wa” eleyi n tọka si awọn ti o ju ẹni kan lọ.

### Ọlọrun ti Ki I Yipada

Paulu n sọ awọn ọrọ daradara wọnyii nipa didá ayé bi a ti kọ ọ silẹ ninu Orin Dafidi 102 nigba ti o wi pe:  “Ati Iwọ, Oluwa, li atetekọṣe li o ti fi ipilẹ aiye sọlẹ; awọn ọrun si ni iṣẹ ọwọ́ rẹ: nwọn ó ṣegbe; ṣugbọn iwọ ó wà sibẹ, gbogbo wọn ni yio si gbó bi ẹwu; ati bi aṣọ ni iwọ o si ká wọn, a o si pàrọ wọn: ṣugbọn bakanna ni iwọ, ọdún rẹ ki yio si pin” (Heberu 1:10–12).  Gbogbo awọn nnkan ti o wà ni ayé ni o n di ogbó wọn o si pada si erupẹ.

Nigba ti awọn ọjọgbọn ninu iwadii awọn ohun ti o ti ṣẹlẹ ninu iran ti o ti lọ ṣaaju ba n walẹ ilu ti o ti fọ́, wọn a maa hú awọn afọku ilu kan lori ekeji jade, wọn a si maa ri apẹẹrẹ ilu meje tabi mẹjọ bẹẹ, ti wọn ti wà ni ayé yii ni akoko ọtọọtọ gẹgẹ bi akọsilẹ iwe itan.  Gbogbo awọn eniyan ti wọn ti gbé ayé ni oriṣiriṣi igba ọtọọtọ wọnyii ni a ti gbagbe.  Ọjọ si n bọ̀ ti a o pa gbogbo ayé paapaa run.  “Awọn imọlẹ oju ọrun yio si ti inu oru gbigbona gidigidi di yiyọ, aiye ati awọn iṣẹ ti o wà ninu rẹ̀ yio si jóna lulu”  (2 Peteru 3:10).  Ṣugbọn  Ọlọrun yoo wà titi laelae.  Laelae ni Oun ti wà, yoo si maa wà titi. Nigba ti Jesu ba pari iṣẹ ti a fi le E lọwọ ni ayé,  Oun yoo dá gbogbo aṣẹ pada fun Baba Rẹ̀.  “Nigba ti a ba si fi ohun gbogbo sabẹ rẹ̀ tan, nigbana li a ó fi Ọmọ tikararẹ̀ pẹlu sabẹ ẹniti o fi ohun gbogbo sabẹ rẹ̀, ki  Ọlọrun ki o le jasi ohun gbogbo li ohun  gbogbo”  (l Kọrinti 15:28).

Bi a o ba pa awọn nnkan ayé yii run patapata bẹẹ, ti awọn nnkan ti Ọlọrun si duro laelae, a le ri i kedere pe ohun ti o ṣe pataki ju lọ ninu ayé wa ni lati jẹ́ ọrẹ Ọlọrun, ki a jẹwọ ki a si kọ awọn ẹ̀ṣẹ wa silẹ, ki a si tún wa bi, ki a si sọ wa di mimọ́ patapata, ki a si maa ṣe ohun wọnni ti o wu U; nigba naa Oun yoo mu wa lọ lati maa ba A gbé ni Ọrun titi lae.  Otitọ ni pe awọn eniyan a maa kú, ara wọn a si maa pada si erupẹ, ṣugbọn ẹmi yoo wà lai ku titi, ni Ọrun-rere tabi ni ọrun-apaadi.  A ni anfaani ti o logo lati sin Ọlọrun ni ayé yii.  Bi a ba kú ki Jesu to pada wa, ti ara wa si pada si erupẹ, ni ipadabọ Rẹ̀ a o ji ara wa dide, pẹlu ara ologo ni a o si ba Jesu gbé ti a o si ba A jọba titi lae.

### Awọn Ọta Jesu

Lẹyin ti Jesu pada si Ọrun lẹyin ti O ti wá gbé ni ayé yii, ti a kan An mọ́ agbelebu, ti O si tun jinde, Ọlọrun wi fun Un pe: “Joko li ọwọ́ ọtún mi, titi emi o fi sọ awọn ọtá rẹ di apoti itisẹ rẹ.”  Nisisiyii Jesu ni ọpọlọpọ ọtá ninu ayé yii.  Olukuluku ẹni ti o kọ̀ lati sin Jesu ni ọtá Rẹ̀.  Ṣugbọn nigba ti Ọlọrun bá rán idajọ wá, gbogbo awọn ọtá Jesu ni a o ṣẹgun ti a o si jẹ niya.

Awọn angẹli jẹ́ ẹda mimọ́ ni Ọrun ti wọn si n ṣe ifẹ Ọlọrun nigba gbogbo.  Ṣugbọn wọn ki i ṣe ẹni nla bi Jesu.  Kò si angẹli kan ti Ọlọrun ṣe ileri irú agbara ati ibukun ti O ṣe fun Jesu, Ọmọ bibi Rẹ̀ kan ṣoṣo fún. Jesu ni O ni gbogbo agbára ti ó wà ni Ọrun ati ni ayé nisisiyii, ṣugbọn Oun n fun eniyan laye lati ṣakoso bi o ti fẹ; nitori naa ni wahala ṣe n wa fun wa nigba gbogbo – ogun ati irọkẹkẹ ogun, ipaniyan, olè ati ohun gbogbo ti i ṣe ibi.  Ṣugbọn nigba ti Jesu ba gba Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun, alaafia yoo wà ni gbogbo ayé. A ni ijọba ododo, bẹẹ ni ki yoo si wahala, airiṣẹ ṣe, ọ̀dá ati iyan mọ́ nibi ti awọn eniyan n gbọran si awọn aṣẹ Rẹ̀.

**Iṣẹ́ ti a rán Awọn Angẹli**

Awọn angẹli ni a n lò lati ọjọ igba ni wá gẹgẹ bi iranṣẹ lati ọdọ Ọlọrun. Awọn angẹli ni o sọ fun Abrahamu pe yoo bi ọmọkunrin kan; awọn ni o sọ ti iparun Sodomu ati Gomorra fun Lọti; angẹli kan ni o sọ fun Sakariah pe yoo bi ọmọkunrin kan ti yoo pe orukọ rẹ ni Johannu, o si sọ fun Maria pe oun ni yoo jẹ́ iya Jesu. Nigba ti Jesu n gbadura ninu Ọgba ti O si wà ninu irora nla nla, awọn angẹli wá lati ṣe iranwọ fun Un. O ni Oun le pe eyi ti o ju legioni mejila awọn angẹli lati daabo bo Oun bi o ba yẹ lati ṣe bẹẹ, ṣugbọn Oun kò fẹ aabo; akoko to fun Un ti a o kan An mọ́ agbelebu. Angẹli kan ni o si di ẹnu awọn kiniun nigba ti Daniẹli wà ninu iho kiniun; bẹẹ ni angẹli kan ni o si ṣi ilẹkun tubu lati dá Peteru silẹ ati awọn Apọsteli iyoku.

Lode oni, Ọlọrun a maa rán awọn angẹli lati ṣe itọju awọn ti o n sin In. Jesu sọ nipa alaini alagbe kan ẹni ti i maa joko ni ẹnu ọna ile ọlọrọ kan, nigba ti o si kú a ti ọwọ́ awọn angẹli gbe e lọ si paradise. A ko le ri awọn angẹli wọnyii, ṣugbọn a mọ̀ pe nigba pupọ ni wọn ti daabo bo wa kuro ninu ewu, ti wọn ti fa wa sẹyin nigba ti a fẹrẹ bọ́ si ẹnu ọkọ ayọkẹlẹ ti n bọ̀, ti wọn gbà wá nigba ti a fẹrẹ ri sinu omi, tabi ti wọn kilọ fun wa nipa ọpọlọpọ ewu miiran. Awọn ajihinrere ni ilu awọn keferi tilẹ ti ri awọn angẹli lori ile wọn nigba ti wọn wà ninu ewu nla nla. "Angẹli Oluwa yi awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀ ká, o si gbà wọn" (Orin Dafidi 34:7). A dupẹ lọwọ Ọlọrun fun awọn angẹli ti n daabo bo wá, ṣugbọn Jesu tobi ju wọn lọ. Oun ni Olugbala wa. Nipasẹ Rẹ ni a le ni iye ainipẹkun.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni awọn wolii Majẹmu Laelae sọ asọtẹlẹ nipa rẹ?
1. Ta ni n sọ ohun ti awọn wolii yoo sọ fun wọn?
2. Ta ni dá ayé?
3. Ẹni meloo ni o wà ninu Iwa Ọlọrun?
4. Ki ni Ọlọrun Baba pe Jesu?
5. Jesu yoo ti wà pẹ́ tó?
6. Awọn wo ni yoo ba Jesu jọba ni ayé?
7. Daruko diẹ ninu iṣẹ awọn angẹli?